28 FEB 1966


# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ỌRẸ AIYE TẸNI GBOGBO LAWA

NO 1,702 SATURDAY FEBRUARY 19 1966 (2D)


## Awọn Ọlọpa Mu Alhaji Opalẹyẹ

ILỌRIN:— Ni ọjọ ọjọ 'Bọ ti iṣe ọjọ ketadinlogun oṣu yi ni awọn Ọlọpa lọ mu Alhaji Z. A. Ọpalẹyẹ ọkan ninu awọn Minista Ijọba ti ẹgbẹ Demọ nṣe akoso rẹ tele ni Ipinlẹ Iwọ[Orun Naijiria] nibiti] o sa lọ ni Ilọrin nigbati rogbodiyan bẹ silẹ lori abayọri idibo si ile Igbimọ Aṣofin Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria eyiti nwọn ṣe ni ọjọ kọkanla oṣu kẹwa ọdun to kọja lọ yi.

Oniwe Irohin wa ni ilu Ilọrin fi ye wa pe ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹdogun oṣu yi ni awọn Ọlọpa lọ mu Alhaji Z A. Ọpalẹyẹ nibiti o ṣe atipo si ni ilu Ilọrin ti awọn Ọlọpa si mu u pada lọ si Ibadan. Irohin na fi ye wa pe awọn Ọlọpa ko sọ ẹsun kankan ti nwọn fi mu Minista Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ana na.

Oniwe Irohin wa tun fi ye wa pe gbogbo awon eru ti awọn Ọlọpa ri ninu ile ti Alhaji Ọpalẹyẹ ngbe ni adugbo kan ti nwọn npe ni Alanamu, Ilorin ni awon Ọlọpa ti gba kuro lowo rẹ.

# GOMINA OLOGUN YAN AWỌN ALAKOSO IJỌBA

IBADAN:— Ni ọjọ Ọjọ 'Rọ ti iṣe ọjọ kẹrindinlogun oṣu yi ni Gomina Ologun Agbegbe Iwọ Orun Naijiria Ọgagun Francis Adekunle Fajuyi yan awọn Igbimọ Alakoso Ijọba mẹjọ ti nwọn yio wa gẹgẹbi Minista fun Ijọba Ologun Ẹkun Iwọ Orun eyiti Gomina Ologun Ẹkun na Ọgagun Adekunle Fajuyi yio wa gẹgẹbi Olori awọn Alakoso Ijọba Ẹkun Iwọ Orun Naijiria,

Ninu awọn Igbimọ Alakoso Ijọba fun Ẹkun Iwọ Orun Naijiria na ni ọkan ninu awọn Ọga ọmọ Ogun ilẹ Naijiria si wa ninu rẹ, bakanna ni ọga agba fun awọn Ọlọpa ti Ipinlẹ Iwọ Orun si wa ninu wọn ati awọn enia mẹfa miran ninu wọn ni awọn oluko agba ninu ile ẹkọ giga Unifasiti si wa ninu wọn. Ikede yi ja de ninu iwe irohin Ijọba Ologun ti Ẹkun Iwọ Orun Naijiria eyiti Ọgagun Adekunle Fajuyi si fi ọwọ si.

Awọn Igbimọ Alakoso Ijọba fun awọn Ẹkun Iwọ Orun Naijiria na ni Olori awọn ọmọ Ogun ti nṣe akoso awọn ọmọ Ogun ti a npe ni (4th Battalion) ni ilu Ibadan ọgagun R E Akahan, Ọga agba awọn Ọlọpa fun Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria Ọgbẹni Emmanuel Olufunwa ati Akọwe agba fun Gomina Ologun Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria Ọgbẹni P T Odumosu

Ninu awọn to tun wa ninu Igbimọ na ni awọn Akọwe agba ninu ile iṣẹ awọn Minista awọn bi Oloye I. O. Dina eto inawo, Ọgbẹni J. O. Longe eto owo ati iṣẹ Aje, Ọgbẹni T M Beckley eto igbẹ ilẹ ati oye Dokita F A Ajayi eto oko, Ọgbẹni S O Asabia eto dida iṣẹ silẹ ati ẹkọ.

Gẹgẹbi ọrọ ti o jade ninu iwe ti Ijọba Ologun na ni o ti ṣe alaye pe awọn Akọwe agba ninu ile iṣẹ awọn Minista na yio ma ni iṣọwọpọ pẹlu awọn Igbimọ Alakoso Ijọba Ipinlẹ to wa nigbati ọrọ to ba ti jẹmọ ile iṣẹ tiwọn ba ti jade ninu eto ti awọn Igbimọ Alakoso fun Ijọba Ologun Ipinlẹ na ba nṣe,

Gomina Ologun Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria na tun ṣe ikede yiyan awọn Igbimọ marun ti nwọn yio ma ṣe eto akoso Ijọba Ipinlẹ na.

Eyiti o jẹ akọkọ ninu awọn Igbimọ marun na ni awọn enia mẹsan ti yio jẹ Igbimọ Oludamọran nipa eto iṣẹ Aje Ipinlẹ na eyiti awọn enia meji yio jẹ oṣiṣẹ Ijọba ti awọn meje yoku si jẹ awọn oluko ninu awọn ile ẹkọ giga ti iṣe Unifasiti.

Ẹniti yio wa gẹgẹbi olori Igbimọ na ni akọwe agba ninu ile iṣẹ minista Alamojuto eto inawo fun Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria, awọn yoku ni akọwe agba ninu ile iṣẹ minista Alamojuto eto idagbasoke iṣẹ Aje, Ọjọgbọn H, A. Oluwasanmi, Ọjọgbọn V. A. Oyenuga ọgbẹni Ayọ Ogunṣẹyẹ Iyaafin Bọlanle Awẹ Dokita S A Aluko Dọkita H M Onitiri ati Dokita O Aboyade.

Ninu iṣẹ ti awọn Igbimọ Oludamọran nipa eto iṣẹ aje na yio ma ṣe nipe ki awọn Igbimọ ṣe ayẹwo nipa eto owo ori ati nipa bi Ijọba yio ṣe ma na owo si lọna to tọ ati eyiti o yẹ nipa eto bi nwọn yio ṣe ṣe ayipada ilana to ti wa nilẹ ninu awọn ile iṣẹ awọn minista ati awọn ile iṣẹ ti Ijọba ipilẹ na ati nipa awọn eto Ijọba ibilẹ lati lemọ ohunti o tọ to si yẹ lati ṣe ni pa bi nwọn yio ṣe fun wọn ni imọran ti eto dagbasoke yio ṣe wa nipa iṣẹ Aje tabi owo ṣiṣe.

Bakanna ni awọn igbimọ na yio tun ma fun awọn onisowo ni imọran lọna ti awọn ngba ya owo ti nwọn yio si tete san pada ta bi bi eto ọja wọn yoo ṣe ma lọ soke si ju ti atẹhinwa lọ

Awọn Igbimọ oludamọran nipa eto iṣẹ aje na yio tun le ni anfani lati le ma ṣe ayẹwo lori bi ilọsiwaju tiṣe wa ninu iṣẹ aje ni Ipinlẹ na

Ninu awọn Igbimọ ti Ijọba Ologun na tun yan ni awọn enia mẹfa kan ti yio wa gẹgẹbi Igbimọ lori eto iṣẹ siṣe tabi lati ma gbe iṣẹ fun awọn enia lati ṣe eyiti Ọgbẹni Odumosu si jẹ Alaga Igbimọ na, Enia marun ni yio jẹ wipe Gomina Ologun ni yio yan wọn nigbakugba eyiti awọn Akọwe agba ninu ile iṣẹ awọn Minista yio pẹlu

Bakanna ni awọn Igbimọ mẹta kan yio tun wa nipa eto iṣẹ siṣe eyiti yio ma jade lati ọwọ awọn Igbimọ na eyiti yio jẹ lati ile iṣẹ Gomina Ologun ati ile iṣẹ awọn Minista eto inawo ati iṣẹ Aje.

Wo oju ewe Kẹfa



Ọlọfa Adekunle Fajuyi
GOMINA OLOGUN IWỌ ORUN

# Iwe si Oloto Irohin Imole

## Il u Iwo Ti Se Tan Lati San Owo Ori

Olotu, Jowo gba mi ni aye ranpe ninu iwe nyin to nta bi akara gbigbona ti o kun fun ogbon ati oye lati dupe lowo Gomina Ologun Ipinle Iwo Orun Naijiria Ogagun Adekunle Fajuyi ninu oro re ti o so ninu ero asoromagbesi ni ojo karun oju yi eyiti o ro gbogbo awon onia Ipinle Iwo Orun lati san owa-ori won fun orisirisi ise ti nwon setan lati se,

Mofi eleyi kesi awon omo ibile Iwo lati san owo ori won ni lasiko fun eto igbesoke Ilu wa nitori a ti mo pe Ijo a Ologun lo le gba wa kuro l'oko eru awon oselu ati pe eleyi si ti da wa loju lori lleri ti nwon ti se pe awon yio lo owo ori wa lona to to ati eyiti o ye fun idagbasoke Ilu wa.

Ohunti o da wa loju nipa oro ti nwon so pe awon yio mu onijekuje egbe Oselu ti o je pe ti ara won nikan ni nwon mo ti nwon ,y o ma mu oju to awon to ngba owo ori patapata nitori eyi mo ro gbogbo awon en a ilu Iwo lati te te san owo ori won lasi— ko nitoripe awon ti o to Ijoba se lo wa lori aga bayi,

Emiti ko ba san owo ori re eyiti han si wa loju pe Ijoba Ologun yio se idajo lo to si Oluware a si mo pe Ijoba Ologbo Akintola ti ba ilu je oja ko te, ise ko si fun awa odo onisowo ko ta ati po a mo pe ohunti o koja ti koja e je ki a tete san owo ori wa lasiko lati le se i e fun idagbasoke ile wa, ki emi Ijoba Ologun gun fun wa amin.

Emi ni
Duro Oyeluade
Oluponna-Iwo.

## Ironsi E Ran Wa Lowo O

Olotu Inu mi yio dun bi e ba legba mi ni aye di e ninu iwe nyin to kun f u n ogbon ati oye lati kesi Oba ilu Eko Alaiyeluwa Adeyinka Oyekan kej et awon ijoye re yoku lati jowo ba awa mekunnu gbe o r o wn yi de odo Ijoba O l o g u n Orile ede Naijiria ati paapo julo fun Gomina Ologun f u Apapo I j ob a Ogagun Aguiyi I o si l a t i bi wa mo oju to awon O j a ti nwon nta ni ilu Eko

Gari ti a ti nra ni s i l e mejl abo (2/6d) tabi s i l e meta (3/) on na lo ti di sile meje (7/) bayi, a si ni ireti pe Ijoba Ologun ile Naijiria yio se iranlowo fun wa lati tete ba wa mu Oju to eyi

Inu wa yio dun bi Ogagun Aguiyi Ironsi ti I s e Gomina agba fun O l o r i Ijoba Ologun ile Naijiria ba le tete se iranlowo f u n wa

Olotu mo dupe fun ti e gba mi ajinde yio ma je fun nyin O

Emi ni,
B O Olaniyo
EKO

BEREFUN OJULOWO EGBOGI_

## "Congreve's Iodo From—Oinment



Atamatase ni egbogi" ADI-BLEGBO" yi je tun itoju gbo gbo orisirisi "EGBO—ESE" ni kiakia bi o ti wu ki jo re ti le pe to, Adielegbo yi bo ni egbe nipa wipe awa ko idoti ni bi eri gbogbo ti ba wa loja egbo patapata jade oju re yio si mo daradara .Lehinna oju egbo yi o ba jin sinu yio jeki oju re hu wa soke, yio si pon daradara tun bakanna ko si mo werewere ni yio si san patapata Alafia de si o niyen ! –

Ri daju gbangba wipe awon sobu ti a da oruko won absaale iwe yi ni ogbe ranse lo ra. Bibeko awon Elere 'hij on ijibiti yio ta 'Adamodi' re fun o mase gba rara

Waterloo Medecine Stores
8, Palm Church Street P. O Box 333 Lagos

# Ha Kini Meyi




OGUN A PA YANMU—YANMU
OLORI ERIN META

Three Elephant Brand mosquito coils dara pupo A ni O dara jul gbogbo ogun a pa yanmuyanmu yoku lo.

O npa yanmuyanmu ninu ile ni kiakia orun re si dara pupo ju gbogbo ogun yanmuyanmu yoku lo. Bakanna ni o si tun yara pa ayan ati idun,

Tete lo ra packet ogun yanmuyanmu, Three Elephant Brand coils tire loni, ki o si danwo; iwo yio ri bi o tise pa gbogbo yanmuyanmu inu ile re ti iwo ati awon omo re yio si sun daradara

Ki o ri daju pe ogun yanmuyanmu; ori erin meta ni nwon mu fun o

Three Elephant mosquito Brand coils yi wa ni sobu Is itaja kakiri Orile ede yi

Distributor
AMOS GBENLE & BROTHERS
34; Docemo Street Lagos.
6 & 11 Balogun Street West

a successful future
means planning **Now!**

Have you planned for the security of your family's future? Start a programme of Life Insurance NOW

with

**GREAT NIGERIA INSURANCE Co. Ltd.,**
INCORPORATED IN NIGERIA

Enquire now for full details of our low cost endowment policy.

HEAD OFFICE,

39/41 MARTINS STREET,
P.O. Box 2314, LAGOS
TELEPHONE 25251.

BRANCHES AND AGENTS THROUGHOUT NIGERIA.

# IDAHUNSI IBERE SIGA MIMU NI CZECHOSLO—VAKIA

Lẹnuloloyi ni awon Igbimo kan ti nwon ope ni alamojuto eto ilera fun awon odomode ni orile ede ile Czechoslovakia se ipade kan lori eto bi awon enia ti se ngmu siga ninu ilu na ati awon enia ti nwon ko mo siga mu ati wipe awon enia ti nwon ngmu siga ninu ilu na.

Siwaju eyi, gegebi irohin ti a ri gba ninu ile ise wa ni opin ose ti o koja lo yi lati ile ise Asoju Ijoba Orile ede ile Czechoslovakia ni Naijiria, a gbo wipe, awon Igbimo eto na ti ko awon ibere kan sinu gbogb awon iwe Irohin ti o wa ni orile ede na.

Nina ohunti awon enia na bere lowo gbogbo awon ara ilu ni wipe nwon fe mo bi siga mima ba dara tabi ko dara lowo gbogbo awon enia.

Ko pe pupo ti nwon bere ibere yi, ti gbogbo awon ara ilu na fi dabun si ibere na, ti gbogbo awon enia ti nwon mo siga mu ati awon enia ti nwon ko mo siga mu si fi esi won ranse si Ile Olu ise awon oluwadi na ninu ile ise won.

Şugbon awon enia na ko tun duro lori gbogbo awon idahun si ibere ti nwon ti ri gba lati odo awon ara ilu, Boya nitoripe, opolopo ninu awon enia ti nwon ngbe inu ilu na ni nwon ko mo iwe tabi ti awon miran mo iwe şugbon ti nwon ko ni aye lati dahun si ibere won na.

Nitori idi eyi, ni awon alase Igbimo na ba tun wa yan awon enia wipe, ki nwon lo kakiri gbogbo arin ilu ati igberiko lati maa lo wadi lowo gbogbo awon enia ti nwon ba ri nibe, ki nwon si mo iye awon enia ti nwon ngmu siga ati iye awon enia ti nwon *ko* mu siga.

Lehin iwadi won, nwon ri wipe, awon enia ti nwon ngmu siga kere lopolopo o ju iye awon enia ti nwon ngmu siga lo,

Fun apere, n gbati nwon se iwadi na, nwon ri wipe, bi awon ba da iye awon enia ti ngmu siga si ogorun ona, ogbon ona pere ni gbogbo awon ti ngmu siga.

Awon adorin (70) ona ti o si seku nile ni nwon ko tile mo siga mu rara ti o je wipe, awon ko tile fe gbo oran re depo ti nwon yio fi kan enu won wipe boya awon yio tile mu.

Şugbon ninu Iwadi ti awon enia na tun se, nwon tun se akiyesi wipe, awon omobinrin ti ngmu siga po lopolopo larin awon obinrin ti nwon nsise ni abe Ijoba.

Awon obinrin ti nwon ko sise ni abe Ijoba tabi ti nwon nse ise *ara*won ko po ninu awon Obinrin ti nwon ngnu siga rara

Bakanna ewe, ni, die ninu awon odomodekunrin ti nwon ko ju omo odun medogun lo ti tun beresi maa mu siga, awon odomobirin *miran* si tun wa pelu ninu won ti o je wipe, ni nkan bi omo odun mewa ni nwon ti beresi maa mu siga tabi ti nwon ti nwon ti fi siga mimu ko arawon nigbati nwon ko tile ti to omo odun mewa rara

Lehin eleyi ni awon enia na wa tun beresi maa se iwadi lowo awon enia na ohunti o fa ti nwon fi ngmu siga tabi onje ni o je fun awon enia na ni ?

Ninu awon idahun wonyi, nwon ri wipe opolopo ninu awon enia na ni nwon nso wipe, bi awon ba mu siga, o nfun awon ni agbara akotun awon si ngri agbara ti awon ba mu siga, ju igbati awon ko ba mu siga lo.

Şugbon awon Igbimo na tun *se* akiyesi wipe, opolopo ninu awon omo ile iwe ni nwon ngmu siga, ti siga mimu *si* ti di bara ku fun awon enia na lati ibere igbesi aiye won.


## Kini O Mu E Ronu Nipa Awọn Asọ Rẹ ?

Bi o ba ni aşo fun fifo tabi lilo ni aşo bi owu (woolen) tapeta, aşo oke, Guluea Brocade ni ti Ọkunrin tabi ti Obinrin. A ni orişirişi aşo ti o ba ni fun fifo tabi ti o ba fẹ yi awo ara aşo na si miran (Changing of Colours]

*Tete Gbe Wa Si Ọdo*

### Iwajọwa Cleaner Enterprises

87, Ọdenfa Street,
Phone 20029 Lagos

Kia ni ao ba ọ fọ, ti iwọ yio si ri gba ni ọsẹ kanna, O le ranşẹ si wa ki a wa ko awọn aşọ rẹ na tabi ki o pe wa lori ẹrọ isọrọ (telifonu) ti nọmba rẹ wa loke iwe yi.

Bakanna ni a si tun nba enia gbọn ilẹ rẹ nu tabi bi o si fẹ kun ile tabi ile işẹ rẹ, işẹ wa tun ni yẹn na Bi enia ba si fẹ kọ ile tabi o şeşẹ kọ tan o si fẹ kun o le gbe fun wa ki a ba kun, ki a si ba şe lọsọ ti yio jẹ oju ni *gbese*, A ni gbogbo işẹ ti o ba ti jẹ ki a tun nkan şe ni o nşe Işẹ tiwa.

Dan wa wo lẹkanşoşo ki o sa ri bi işẹ wa ti dara to. Owo pọku ni a si ngba.


## YẸ IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan 22 Feb 20) O dabi ẹnipe ara fẹ mu ọ loni ise ni ki o şe suru ki o si ma wadi ọrọ daju ki o to gbamu ki o si fi ori ti awọn işoro ti o ba wa ni nu işẹ rẹ

PISCES (Feb 21 Mar 20) O yẹ ki o jẹ anfani ire to mbẹ fun ọ loni ki o si yanju gbogbo Işoro ti o mbẹ fun ọ ki o ma si şe fi ibinu da ẹjọ ni idakuda

ARIES )Mar 21 April 20) Oju ọna ti o tọ lo wa ma tọ niso, şugbọn ki o ma lo ọgbọn ori re nipe gegebi o ti şe na wawu ki o maşe na inakuna

TAURUS (April 21 May 20) Ise re ojojumo su ọ o si nda ọ lamu nitorina o ni lati şe suru nitoripe papọ

LEO July 23 Aug 22 Bi o ba ngbero kan lati ba enia kan şe adehun papọ ot tọ inu ati ododo ni ki o sọ nibẹ nitoripe adehun ti ẹo şe ki işe nkan ti enia le dalẹ rẹ

VIRGO Aug 23 Sept 23 Orişirişi ọrọ li o wa fun ọ lọna kini odabi pe arẹ fẹ mu ọ ọna keji okan rẹ nfẹ ki ẹ jọ şadehun nitoripe ọkan rẹ nda si meji.

LIBRA Sept 24 Oct 23 Bi o ba le ma ba işẹ rẹ lọ iwọ yio fi ọpẹ fun Oluwa ti o fun ọ ni ọgbọn

SCORPIO Oct 24 Nov 22 Ire nbẹ pẹlu rẹ lọna gbogbo ọrọ ti o ba ba gbogbo enia sọ yio gba si ọ lẹnu

SAGITTARIUS Nov 23 Dec 21 Pirikiti ni ara rẹ lọ ni şugbọn maşe jẹki aşeju ba ọla rẹ jẹ ire ni ọro rẹ yio jẹ

CAPRICORN Dec 22 Jan 21 Ire mbẹ fun o loni o na gbogbo awon ẹniti o fẹ yio ma nifẹ rẹ siwaju ko nşe ohun ti o rọrun

*GEMINI* (*May 21 June 20*) Şe eto gbogbo ohunti iwọ yio şe oni ki o si fi ara mọ eto na yio si yọri si rere.

CANCER (June 22 July 20) Ọjọ itunu ni oni jọ iwọ yio si ma işẹ rẹ lọ gegegere maşe jafara ki o şe leto ni gbogbo okan yio fi lọ.


## KERE O

Njẹ o ti ni ninu "IWE ITAN ODUDUWA ọsẹ şẹjade ?

Ha ! Kosemani ni iwe na jẹ fun ọmọ Yoruba Iwe na kun fun itan Işẹdalẹ Yoruba. Kedere ni aworan Oduduwa ati ti ọmọ rẹ han ninu rẹ.

Maşe jẹki nwọn rohin itan ilu rẹ fun ọ
3/- pere ni. Postage 9d

Tete fowo tirẹ ranşẹ si:-

ẸSAN KOGBOGUN SERVICE

8 Idumagbo Avenue Lagos Nigeria

# Ikilo Mi Fun Enia Aiye Gbogbo

Ẹnyin enia ile Naijiria mo si fẹ ki ẹ gba ọrọ mi yi ki ẹ si fiṣe iwa hu ati pe ẹniti o ba ni eti ki o gbọ Mo ri pe iya ṣẹṣẹ bẹrẹ ni nitorinaa awọn ẹ̣ja meji ni mo ri ti nwọn koju ija si ariwọn nitorina mọ wipe iku enia yio dọ si y'o si jẹ iku airotẹlẹ.

**Lati Owo**



**Woli Kogberegbe**

Ninu iran mi mo ri e awọn ẹgbẹ UPGA ni o'uwa fẹ fun ni Ijọba o ṣugbọn awọn enia yio ma inwẹ ni nu ẹjẹ ki owo wọn to le tọ Ijọba na o.

Oluwa sọ fun mi pe ọpọ lọpa Ọlọla ti ku ninu idibo yi ati nigbati idibo yi ba pari ija nla kan yio bẹ silẹ larin igboro nitori ọrọ idibo.

Mo ri pe awọn ọlọla yio ṣe ipade kan nilu Eko ija ni nwọ yio fi pari rẹ ti nwọk yio si tuka nibẹ oluwa yio binu si awọn ọlọla Enia meta yio fi aye silẹ ọkan ninu wọn ọlọla. Minista ati oba ọkan yio si ku okiki yio kan si ọna idalẹ Nigbana ki gbogbo enia lo mura si adura ohunti wa fẹ se eyi.

Mo ri pe Awelowo yio jade lọgba ẹwọn ṣugbọn nitori eyi ẹ gba adura lati fi ran lọwọ ki ẹmi rẹ le pẹẹ diẹ si otitọ ni Oluwa to wipe ẹgbẹ A G ati NCNC ni yio wọle ṣugbọn kinwọn to wọle na okiki yio pọ ẹ jẹ yio si pọju alafia lọ oluwa sọ pe ki igbagbọ ati Imọle panapọ lọ na gba adura.

Iyan yio si ma ja awọn Alaimọkan nitorina ki awọn Imọle ati igbagbọ parapọ ki nwọn si ma gba adure lati fi ran aiye lọwọ

Bi o ti wu ki o ri ẹjọ ti awon mu Adegbenro si ko ni ojetu rara Nw n ki yio ri nkankan ṣe fun sugbon awọn A G ni mo ti ri ijoba lẹhinti awọn ẹgbẹ UPGA A ba gba ij ba tan iia yi si bẹ silẹ larin N C N C atı A G ṣugbon Oluwa yio ṣẹgun fun wọn Mo ri pe Ọdẹku yio jẹ okan ninu awon Minista na

Oluwa yio gbe wa leke aiye o ẹmin

GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ATI OGO

NIPA **DYNAMIREN** TỌNIKI

ALE-IBI-ALE Egbogi Tọ ki amọnu, titun ti gbogbo ara Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju fun Agbara ati Ajẹbidan ṣẹ lara agbalagba Ọkunrin ati Obinrin gbogbo



Bi arẹ ara ba nmu ọ, ni gbakugba fun wahala tabi iṣẹ ṣiṣe ti o ko le jẹun dara dara, tabi ki o male sun da da de ọkan lọsan tabi awọn ṣan ara rẹ gbogbo ki ṣe fun daradara ti Emi Breath inu ko ba kunlẹ daradara wọn iṣẹ tabi wahala sise tabi inu awọn ailera gbogbo nyin ti ọjọ ori (age) ba ti kọja ọgbọn ọdun si adọrin tabi jubẹ lọ mọ daju pe DYNAMIREN ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara rẹ di ọtunp pata oju rẹ yio si walẹ re kete alafia ati igbadun de Bere Dynamiren yi ni Ṣọbu awọn i-

Waterloo Medicine Stores
8 PalmChurch Street Lagos
22878 Lagos Nigeria (Oja Ita Faaji)
UNITED DRUG CHEMIST
Alli Street Lagos

NIGERIAN MEDICINE STORES
Tinubu Square Lagos
LAGOS ISLAND CHEMIST
Nnamdi Azikiwe Street,Lagos
UNITED DRUG CHEMIST
Alli Street, Lagos.

ATI NI ṢỌBU
IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE BỌLA
IBADAN


# Iwe Itaja 1966

Idamu owo ha wa fun ọ bi
Abiku ha nyọ ọ lẹnu bi
Airi iṣẹ ṣe ha wa fun ọ bi
Ailern mba ọ ja bi
?

Iwọ le bọ ninu gbogbo wahala aiye wọnyi ti iwọ ba ra ninu awọn ohun Ijinlẹ Iṣẹdalẹ Yoruba ti a to lẹsẹsẹ si isalẹ yi.

1 Iwe Egbogi Ajẹbidan 25/— di 22/6
2 Iwe Afọṣẹ Isẹdalẹ Yoruba ati Ps lm Aj.bidan 4/6 di 3/6
3 Iwe Itumọ Ala ati Ogun Wibẹjẹbẹ 4/6 di 3/6
4 Iwe Egbogi Awogba Arun 20/— di 17/6
5 Iwe Ilana Ifa Yanrin tite ati etutu ṣiṣe 20/- di 17/6
6 Gbedegbẹyọ Hausa 3/—
7 Iwe Aniyan Irun 2/— di 1/—
8 Turari Iṣegun Ajẹ ati Itaja 10/6 Pangolo 2/6 paket

Fi Owo ranṣe si
J, O, SHOYINKA
P, O, Box 159
MUSHIN
tabi
9, Iyala Street Oduabọrẹ, Mushin

# IROHIN IMỌLẸ

ỊMỌLE ORE AIYE TẸNI GBOGBO LAWA

NO 1,702 SATURDAY FEBRUARY 19, 1966 (2 D)

## Awọn Ijoye Ilu Owu Ki Ọga'gun Fajuyi

OWO:— Ninu irohin kan to de ile-iṣẹ wa ni ọsan ọjọ Ọjọ 'Ru lati ọwọ Igbimọ awọn Ijoye ti adugbo Ijẹbu Quarters ni ilu Ọwọ ni awọn Ijoye na ti ṣe alaye ninu iwe ti nwọn kọ si Gomina Ologun Agbegbe Iwọ Orun Naijiria Ọga'gun Adekunle Fajuyi ni awọn Ọba na ti ni awọn ki i ku orire lori aga ti o wa gẹgẹbi Gomina Ologun fun Ijọba agbegbe Iwọ Orun Naijiria.

Ninu iwe ti awọn Ijoye na kọ si Ọgagun Francis Adekunle Fajuyi ni nwọn ti ṣe alaye lori iwa ti Ọba Ọlagbegi Ọlatẹru Keji Ọlọwọ ti ilu Ọwọ nhu pẹlu awọn Ijoye ilu na nipa pe Ọba na nlo ipo rẹ gẹgẹbi Ọba lati fi iya ma jẹ awọn Ijoye ilu.

Awọn Ijoye ilu Ọwọ na tun ṣe alaye pe Ọba Ọlọwọ ti ilu Ọwọ si nlo ipo rẹ gẹgẹbi Ọba ilu na ati pe o nlo Ijọba ti o ti wa ni Ipinlẹ Iwọ Orun tẹlẹ lati le ma fi iya ma jẹ awọn Ijoye eyiti awọn Oloye na tun ṣe alaye pe Ọba na si pa oye Ojomo ti ilu Ọwọ rẹ lori iwa ikorira ti Ọba na ni si awọn Ijoye ilu na eyiti o tun fi ge ilu na ku si gẹgẹbi o ti ṣe wa tẹlẹ.

Awọn Ijoye na tun kesi Ọgagun Fajuyi lati ṣe iwadi si ohunti o le mu Ọba Ọlọwọ pa oye Ọjọmọ rẹ ni ilu Ọwọ ati paapa akitiyan Ọba Ilu Ọwọ lori iwa to nhu si awọn enia ilu na.

# IJỌBA DA AWỌN ADAJỌ IJỌBA IBILẸ DURO

IBINNI:- Ninu irohin kan to de ile iṣẹ wa ni ọjọ ọjọ 'Bọ ti iṣe ọjọ kẹtadinlogun osu yi ni irohin fi ye wa pe Gomina Ologun ti Ipinlẹ agbedemeji Iwọ Orun Naijiria Ọgagun David Ejoor ti da gbogbo awọn Adajọ ile ẹjọ ti Ijọba ibilẹ ti ipinlẹ na ati awọn isongbe awọn adajọ na ni nwọn dad ro lẹnu iṣẹ wọn g gẹbi adajọ ninu awọn ile ẹjọ ti Ijọba Ibilẹ ni jakejado Ipinlẹ na.

Ninu irohin to jade ninu iwe ijọba Ipinlẹ na eyi ti nwọn npe ni (Gazett) ni ikede na ti jade pe ki yio si awọn ile ẹjọ ti Ijọba ibilẹ mọ ni Ipinlẹ na.

Ni u iwe Ijọba Ipinlẹ na ni o ti ṣe ikede pe lati ọjọ ọjọ'Ru ti iṣe ọjọ kẹrindinlogun oṣu yi ni awọn adajọ na o ti ti ipo wọn sile gẹgẹbi adajọ ile ẹjọ ti Ijọba ibilẹ ni Ipinlẹ na. Bakanna ni Gomina Ologun si paṣẹ pe ki w n ti awọn ile ẹjọ na pa patapata

Ninu iwe Ijọba na ni o ti ṣe ikede pe ki nwọn gbe gbogbo awọn ẹjọ ti nwọn ba ni lati ṣe ninu awọn kotu Ijọba ibilẹ jakejado Ipinlẹ na lọ si ile ẹjọ kekere to jẹ ti Ijọba ati pe gbogbo awọn ẹjọ ti o ti wa ninu ile ẹjọ ti Ijọba ibilẹ ni Ipinlẹ na ni awọn yio bẹrẹsi ni ma gbọ lati ọjọ ọjọ'Bọ ti i ṣ e ọjọ kẹtadinlogun oṣu yi ni ile ẹjọ kekere ti Ijọba

Ninu iroh n kan ti o tun de ile iṣẹ wa ni ọsan ọjọ ọjọ Bọ ti iṣe ojo kẹtadinlogun oṣu yi ni awon obinrin onisowo ti ilu Oshogbo ti ṣe alaye pe awon faramo eto ti Gomina Ologun Ipinlẹ Iwo Orun Naijiria ṣe eyiti o fi da gbogbo awon adajo kotu Ijoba ibilẹ Ipinlẹ na d ro

Ninu oro awon ẹgbẹ obirin onişowo ilu Oshogbo ni nwon ti ṣe alaye pe awon faramo gbogbo eto ti Gomina Ologun Ipinlẹ Iwo Orun Naijiria nipa d i J a awon adajo ile ejo ibile na duro

Ninu irohin to tun de ile iṣe wa ni osan ojo ojo'Bo ti iṣe ọjọ kẹtadinlogun oṣu yi ni awọn egbe ọdọ ti ilu Ondo ti kesi Gomina Ologun Ipinle Iwọ Orun Naijiria lati yan Igbimọ Oluwadi si eto ile iṣẹ oko roba ti nwọn npe ni (Ọda Akure Rubber Estate) ti o wa ni Araromi, Ọbu

Awọn ẹgbẹ ọdọ ilu Ondo sọ eyi ninu iwe ikini ka orire ti nwọn kọ si Ogagun Adekunle Fajuyi gẹgẹbi ipo titun ti nwọn gẹsọ yan si gẹgẹbi Gomina Ologun fun Ijọba Ologun Ipinlẹ Iwọ Orun Najiria.

## Gomina Yan Awọn Alakoso Ijọba

### Lati Oju Ewe Kini

Ninu awon enia ti yio tun wa ninu Igbimo na ni awon enia ti yio wa ninu awon ile iṣẹ I j o b a eyiti nwon yio jẹ Igbimo m;ta ati pe awon Igbimo eto sbo fun Ijoba Ipinlẹ Iwo Orun Naijiria eyiti awon marun yio jẹ Akowe agba fun Gomina Ologun ti Ipinlẹ na eyiti yio wa gẹgẹbi Alaga Igbimọ eyiti awon ọga agba fun awon ẹmo ogun ati Ọga agba fun awon Ọlopa ti Ipinlẹ Iwo Orun Naijiria

Awon Igbimọ na yio ma aiṣẹ lori awon iṣẹ eyiti o to ẹgbaa pọnun (£2,000) ti o jẹ pe nwọn yio ma gbe fun awọn oṣiṣẹ ti o ngba iṣẹ se.

PHILIPS

for

RADIO

PHILIPS

### LATI OJU EWE KINI

Oniwe Irohin wa ni ilu Ibadan fi ye wa ninu irohin rẹ pe awọn Ọlọpa ko ti fi Alhaji na sile bayi ati pe o si wa ni ọgba awọn Ọlọpa nu nibiti nwọn ti nṣe iwadi awọn ọrọ kan lọwọ re

Oniwe Irohin wa kan ran wa leti pe laipe yi ni Alhaji Z A Opaleye so ni ilu Ilọrin pe on ko ri awọn iyawo on ati awọn omo on pelu ati pe on kọ le sọ pe ibi bayi ni nwon wa

Printed and Published By Modupe Pristin Press16, gbte Street, Lagos Phone 21985
Editor: TUNJI ADEOSUN 25 Branco Street Lagos 19/2/66